# ORISUN ODODO TOOTỌ

## Romu 2: 17-29; 3:1-31; 9:30-33.

## ẸKỌ 382 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Nitoripe nipa iṣẹ ofin, a ki yio dá ẹnikẹni lare niwaju rẹ̀: nitori nipa ofin ni imọ ẹ̀ṣẹ ti wá" (Romu 3:20).**

**I. Idalẹbi Awọn Ju nipasẹ Ofin**

1. Gbogbo awọn ti o n pe ara wọǹ ni Ju kò rin gẹgẹ bi Orin, Romu 2:17-25; Johannu 5:45
2. Awọn Keferi alaikọla ti o ba pa Ofin mọ́ jẹ idalẹbi fun awọn Ju ti ko pa Ofin mọ́, Romu 2:26, 27; Iṣẹ Awọn Apọsteli 10:1, 2
3. Isin ẹmi tootọ dipo ti ode ara ni n sọ ni di Ju tootọ, Romu 2:28, 29; Johannu 4:20-24

**II. Ododo Ọlọrun ati Ẹbi Ẹ̀ṣẹ Eniyan**

1. Awọn Ju ni anfaani pupọ, Romu 3:1, 2; 1:16; Iṣe Awọn Apọsteli 3:26, 3:46, Orin Dafidi 47:19, 20
2. Ikuna ti diẹ ninu awọn Ju ni ki I ṣe ẹjọ Ofin, Romu 3:3, 4; Heberu 4:2
3. Ododo Ọlọrun fara han ninu idajọ Rẹ̀, Romu 3:4-8; Ifihan 16:5-7
4. Ko si ẹni ti o da lare nipa iṣẹ rere ṣiṣe, Romu 3:20; Titu 3:4; Galatia 2:16
5. Gbogbo eniyan ti ṣẹ, Romu 3:9-18; Orin Dafidi 14:1-2; Isaiah 53:6

**III. Idalare nipa Igbagbọ́**

1. Nipa igbagbọ ni ododo ti i wá, Romu 3:21-28; Habakuku 2:4
2. Ọlọrun n da Ju ati Keferi lare nipa igbagbọ, Romu 3:29-31; Galatia 3:7-9
3. Israẹli tase oju ami, Romu 9:30-33.

### ALAYE

**Isin Ọ̀de ara**

Awọn Ju ti n kọ́ ẹlomiran ni Ofin di ẹlẹbi nipasẹ Ofin kan naa ti wọn fi n kọ ni. Gbogbo ẹsin wọn ni wọn n ṣe gẹgẹ bi ilana Ofin ṣugbọn ki I ṣe ninu ẹmi. Jesu wi pe, "Ẹnyin Farisi a ma fọ̀ ode ago ati awopọkọ́; ṣugbọn inu nyin kun fun irẹjẹ iwa-buburu" (Luku 11:39). Wọn n ṣe ọfintoto nnkan keekeekee ti ode ara ṣugbọn wọn "fi ọran ti o tobiju ninu ofin silẹ laiṣe, idajọ, ãnu, ati igbagbọ́" (Matteu 23:23). "Egbé ni fun nyin, ẹnyin Farisi! Nitoriti ẹnyin a ma san idamẹwa minti, ati rue, ati gbogbo ewebẹ̀, ṣugbọn enyin gbojufò idajọ ati ifẹ Ọlọrun" (Luku 11:47).

Eniyan pupọ lọde-oni ni wọn n pe ara wọn ni Onigbagbọ, ti wọn si jẹ onitara ninu iṣẹ rere iṣe, ṣugbọn ti wọn kò ni gbala tootọ gẹgẹ bi awọn Ju wọnyii. Wọn n ṣe igberaga ninu imọ ti Iwe-Mimọ́, wọn si n gbé igbesi-ayé ọmọluwabi ṣugbọn igbẹkẹle wọn wà ninu gbigba Jesu gbọ́ nipa ti ọgbọ́n-ori. Wọn kuna ironupiwada tootọ. Wọn jẹ ope si oore-ọfẹ Ọlọrun ti o n yi eniyan pada ti o si n jẹ ki a gbe igbesi-aye ailẹṣẹ. Wọn n wi pe awọn wà labẹ aabo Ẹjẹ Kristi, ṣugbọn wọn jẹbi awọn ẹṣẹ kan naa ti a n fi lọwọ awọn wọnni ti kò tilẹ jẹwọ iwa-bi-Ọlọrun. "Iwọ ti nṣogo ninu ofin, ni riru ofin iwọ bù Ọlọrun li ọla kù?" (Romu 2:23).

A n fi ilana ikọla ati ati ipamọ awọn ilana miiran ti a le fi oju ri ti a kọ sinu Ofin mọ awọn awọn Ju, gẹgẹ bi Onigbagbọ miiran lode oni ti n gbé agbelebu kọrun tabi ki o mu un lọwọ tabi ki o wọ ohun ami miiran lati fi i hàn bi Onigbagbọ. Awọn Ju ti bẹrẹ si wo awọn ami ode-ara wọnyii bi ohun idaniloju ti n fi wọn han bi olododo. Eyi ni pe bi wọn ba tilẹ so paali kan mọ ara, eyi jẹ ijẹri si ododo wọn. Ẹ jẹ ki a wo o lọna bayii bi a ba beere lọwọ ẹni kan pe, "Onigbagbọ ni ọ bi?" Oun a si tọka si akọle kekere ti o wa lara aṣọ rẹ̀, a si fesi bayii: "Dajudaju, iwọ kò ri ami ti o wa lara mi yii ni?"

**Ododo ti Inu**

Ninu Episteli ti awọn ara Romu, Ọlọrun n ba awọn Ju sọrọ pe ki i ṣe isin ode-ara ni o n sọ eniyan di olododo, gẹgẹ bi ikọla kò ti ja mọ nkankan ayafi bi a ba n gbe igbesi-aye iwa-mimọ́. Bi ẹni kan bá n pe ara rẹ̀ ni Ju, ti o si n fọnnu pe a kọ oun ni ila, kò jẹ nnkan afi bi o ba n gbé igbesi-ayé iwa-bi-Ọlọrun.

Keferi kan wà ti o n gbé igbesi-ayé iwa-bi-Ọlọrun ṣugbọn a kò kọ ọ́ nila nipa eyi ti o le fọnnu. Bawo ni o ṣe le gbé igbesi-ayé iwa-bi-Ọlọrun? Nitori igbagbọ́ rẹ̀ ninu Jesu ni. Ododo, gẹgẹ bi a ti fi hàn, ki i wá nipa iṣẹ Ofin bi ko ṣe nipa igbagbọ́. Otitọ ni eyi, a baa jẹ́ Ju tabi Keferi. Kò ṣẹṣẹ di igba ti Keferi ba pa ilana Ofin mọ́ ki o to di Onigbagbọ́. Bakan naa ni Ju kò le di Onigbagbọ́ nipa ilana Ofin bi kò ṣe nipa igbagbọ́ ti o ní ninu Jesu.

**Titabuku si Ọlọrun**

**"**Orukọ Ọlọrun sá di isọrọ-buburu si ninu awọn Keferi nitori nyin" (Romu 2:24). Ikuna awọn Ju lati gbé igbesi-ayé giga ti wọn n fi ẹnu jẹwọ fi àye silẹ fun awọn Keferi lati sọrọ odi si orukọ Ọlọrun. Nigba ti Dafidi ṣẹ̀, Wolii Natani wi pe, "Nipa iwa yi, iwọ fi aye silẹ fun awọn ọta OLUWA lati sọ ọ̀rọ ọ̀di" (2 Samuẹli 12:14). Ayé n fẹ ri eso Isin Kristi ninu igbesi-aye awọn wọnni ti a n pe orukọ Rẹ̀ mọ́. "Ki olukuluku ẹniti npè orukọ Oluwa ki o kuro ninu aiṣododo" (2 Timoteu 2:19). Iwa Onigbagbọ lẹnu iṣẹ́ rẹ̀ ni lati jẹ eyi ti yoo fi ọla fun Ọlọrun. "Ki gbogbo awọn ti iṣe ẹrú labẹ irú mã ka awọn oluwa ti o ni wọn yẹ si ọla gbogbo, ki a má ba sọrọ-odi si orukọ Ọlọrun ati ẹkọ́ rẹ̀" (1 Timoteu 6:1). A n gba awọn ọdọmọbinrin niyanju lati "fẹran awọn ọkọ wọn, lati fẹran awọn ọmọ wọn, lati jẹ alairekọja, mimọ́, oṣiṣẹ́ nile, ẹni rere, awọn ti ntẹriba fun awọn ọkọ wọn, ki ọrọ Ọlọrun ki o maṣe di isọ̀rọ-ọ̀di si" (Titu 2:4, 5).

**Anfaani ti Awọn Ju Ni**

Awọn Ju ni anfaani kan ju awọn Keferi lọ ni ti pe awọn ni Ọlọrun yàn lati jẹ ẹnu nipa eyi ti Ofin Rẹ̀ yoo fi di mimọ̀ fun gbogbo ayé. "Awọn li a fi ọrọ Ọlọrun le lọwọ." Ọlọrun fun Israẹli ni ofin ododo lati ṣe akoso wọn. "Orilẹ-ède nla wo li o si wà, ti o ní ilana ati idajọ ti iṣe ododo to bi gbogbo ofin yi, ti mo fi siwaju nyin li oni?" (Deuteronomi 4:8). Wọn mọ nnkan ti a fẹ lọwọ wọn, ati pe ẹ̀ṣẹ ni riru Ofin. Imọ Ofin yii pẹlu n mu igbala wá fun kiki awọn wọnni ti wọn ni igbagbọ ninu Jesu Kristi. "Gbogbo wa ti ṣina kirikiri bi agutan, olukuluku wa tẹle ọ̀na ara rẹ̀" (Isaiah 53:6). "Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀ ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun" (Romu 3:23).

**Igbagbọ́ ati Ikunà**

"Njẹ ki ha ni bi awọn kan jẹ alaigbagbọ? aigbagbọ wọn yio ha sọ otitọ Ọlọrun di asan bi?" (Romu 3:3). Agabagebe ati ikunà awọn kan lati gbe igbesi-ayé giga ti Ihinrere n beere ko fi han pe ohun ti kò ṣe e ṣe ni lati gbé iru igbesi-aye bẹẹ. Njẹ a ha le titori pe awọn kan kunà lẹnu iṣẹ ki a si wi pe kò ṣe e ṣe fun eniyan lati ṣe aṣeyọri mọ́? A ha le titori pe a ri ayederu owo kan ki a si wi pe kò si ojulowo owo mọ́?

Ọ̀dodó lili funfun a maa dá yatọ lori ilẹ dudu, bẹẹ ni itanṣan iná a maa tan yinrinyinrin ninu okunkun. Bakan naa ni imọlẹ Ihinrere Kristi maa n fara hàn ni akoko ti Israẹli ba wà ninu ikuuku aigbagbọ́. "Ṣugbọn Ofin bọ si inu rẹ̀, ki ẹ̀ṣẹ le di pupọ. Ṣugbọn nibiti ẹ̀ṣẹ di pupọ, ore-ọfẹ di pupọ rekọja. Pe, gẹgẹ bi ẹ̀ṣẹ ti jọba nipa ikú, bẹni ki ore-ọfẹ si le jọba nipa ododo titi iye ainipẹkun nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa" (Romu 5:20, 21). Ofin wá lati fi ẹ̀ṣẹ hàn; Jesu wá lati mu ẹ̀ṣẹ kuro. "Awọn ẹniti a ndalare lọfẹ nipa õre-ọfẹ rẹ̀, nipa idande ti o wà ninu Kristi Jesu: Ẹniti Ọlọrun ti gbe kalẹ lati jẹ ètutu nipa igbagbọ́ ninu ẹ̀jẹ rẹ̀, lati fi ododo rẹ̀ hàn nitori idariji awọn ẹ̀ṣẹ" (Romu 3:24, 25).

A kò le pa ẹmi Ofin mọ nipa ṣiṣe iṣẹ Ofin bikoṣe nipa igbagbọ ninu Kristi. "Nitoripe nipa iṣẹ ofin, ki yio dá ẹnikẹni lare" (Romu 3:20). Gbogbo awọn ti wọn gbe igbe-aye iwa-bi-Ọlọrun ni akoko igba Ofin ṣe bẹẹ nipa igbagbọ́. A da awọn Ju lare nipa igbagbọ, ani labẹ Ofin, nitori gbogbo ododo tootọ n tipasẹ igbagbọ wá. Ọlọrun jẹ Ọlọrun awọn Keferi pẹlu ti a da lare nipa igbagbọ́.

Kò si ẹni kan nipa iwa rere tabi iṣẹ rere rẹ̀ ti o le wu Ọlọrun "Li aisi igbagbọ́ ko ṣe iṣe lati wu u" (Heberu 11:6). Ibaa ṣe Ju tabi Keferi, ọna kan ṣoṣo ni o wà ti a fi le wu Ọlọrun, ọna naa ni nipa igbagbọ́ ninu irapada ti Jesu pese silẹ fun wa nipa ikú Rẹ̀ lori Agbelebu. Kò ṣe e ṣe lati gbe igbesi-aye

Onigbagbọ nipa agbara wa. Ṣugbọn o ṣe e ṣe lẹyin ti igbagbọ ba ti mú igbala wa sinu ọkàn wa, ti Ọlọrun si ti fun wa ni ipá lati lọ ki a ma dẹṣẹ mọ́.

**AWỌN IBEERE**

1. Ninu ki ni awọn Ju n fi igbẹkẹle wọn si?
2. Ta ni a le fi iwa awọn Ju wé lọjọ oni?
3. Anfaani wo ni awọn Ju ni?
4. Ki ni itumọ aiṣododo wa n yin ododo Ọlọrun (Romu 3:5).
5. Nipa ki ni a n dá awọn Keferi lare? Awọn Ju n kọ́?
6. Ki ni ṣe ti ọwọ Israẹli kò tẹ ododo?
7. Ta ni a n tọka si bi okuta ikọsẹ ti a gbé kalẹ ni Sioni?
8. Ta ni awọn ọ̀rọ wọnyii n tọka si: “Kò si ẹniti nṣe rere, kò tilẹ si ẹnikan?”
9. Ki ni Ofin mú wá?
10. Ki ni Jesu ṣe ti Ofin kò le ṣe?